# Kíkọ́ Èdè Yorùbá Gẹ́gẹ́ Bí Èdè Àbínibí: Àkóónú Àtí Ọgbọ́n Ìkọ́ni

Solomon Ọláńrewájú Mákindé
Lagos State University, Nigeria
lanremakinde2015@gmail.com; lanremakinde05@yahoo.com

## Àsamọ̀

Nínú àpilẹ̀kọ yìí, mo ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ lórí àkóónú, ọgbọ́n-ìkọ́ni, ọgbọ́n ìṣètò, àti ìlànà àyẹ̀wò fún àwọn olùkọ́ tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí. Mo ṣàfiwé ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin akitíyan àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí àti àwọn olùkọ́ tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́bẹ́ bí èdè àjòjì tabi èdè àkọ́kúntẹni.

## Ìfáárà

Ipa tí èdè ń kó nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá kò ṣe é díwọ̀n rárá nítorí pé a kò lè ṣe láìsí èdè. Ìgbésí ayé ẹ̀dá kò lè ní ìtumọ̀ láìsí èdè. Fún ìbáṣọ̀rọ̀ láàrín eni méjì, tàbí ẹgbẹ́ méjì, fún ìgbọ́ra-ẹni-yé, fún ìtanijí lórí ohun tó ṣe pàtàkì láyé ẹni tàbí ti àwùjọ, àní fún ìdàgbà-sókè ẹ̀kọ́ (Kolawole, 2003), èdè ṣe pàtàkì púpọ̀. Èdè Yorùbá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn èdè mẹ́ta tí Ijọba Àpapọ̀ gbé ga ní ilẹ̀ Nàìjiríà gẹ́gẹ́ bí àwọn èdè tó pàtàkì jùlọ, ni ti pé àwọn ti ń sọ èdè náà pọ̀ jù àwọn ti n sọ àwọn èdè yòókù lọ (NPE, 2004).

Ní ìhà àríwá orìlẹ̀-èdè Nàìjìríà, èdè Hausa lo gbajú-gba-jà; ní ìhà ìlà-oòrùn, èdè Ìgbò ló gbajú-gbajà; bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ nì ó jẹ́ pé èdè Yorùbá ni ó gbajú-gbajà ní ìwọ̀-oòrùn Nàìjíríà. Àmọ́ ohun tí ó jẹ ìjọba lógùn ni ìṣọkan orile-èdè Nàìjíríà nítorí pé bí àwọn ẹ̀yà kan bá ń kọ́ èdè ẹ̀yà mìíràn, èyí yóò ṣokùnfà ìgbọ́-ra-ẹni yé, èyí tí yóò sì yọrí sí ìṣọ̀kan. Àwọn onígbàgbọ́ ọmọlẹ́yìn Krístì ni wọ́n ṣe agbátẹrù fún-kíkọ́ èdè Yorùbá ní àsìkò ìjọba Gẹ̀ẹ́sì.

Ìgbìmọ̀ Àgbà Yorùbá (Yorùbá Council of Elders) ní 2002 tọ́ka sí i pé àwọn orìlẹ̀ tí wọ́n jẹ́ Yorùbá ni iwọ̀nyí: Àjàṣẹ́, Àkókó, Àpọ̀ì, Àwórì, Bunu, Edo, Èkó, Ègùn, Ẹ̀gbá, Èkìtì, Ìbàdàn, Igala, Ìgbìrà, Ìgbómìnà, Ìjẹ̀bú, Ìjumu, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ, Ìṣẹ̀kírì, Iyàgbà, Màgango, Nupe, Ògòrí, Ògbómọ̀ṣọ́, Òǹdo, Ọṣun, Owe, Oworo,

Ọwọ̀, Ọ̀yọ́, Rẹmọ, àti Yewa. Bí a bá wo àwọn orílẹ̀ wọ̀nyìí, ó jọun pé ó jú ẹ̀ka èdè ni àgbègbè ìwọ̀-oòrùn Afíríkà, àti àwọn Orílẹ̀-Èdè bí i Brazil Cuba West Indies ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lo (Mákinde, 2003:16). Nínú ìpínrọ̀ kínní, a mẹ́nu bàá pé èdè wúlò fún ìdàgbàsókè ẹ̀kọ́. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé a lè kọ́ èdè gẹ́gẹ́ bí àkànṣe iṣẹ́ ní ilé-ẹ̀kọ́, a sì lè lo èdè gẹ́gẹ́ bi ohun èlò ìdánìlẹ́kọ̀ọ́. Láìṣe àníàní, ìbáṣepọ̀ alọ́májàá ló wà láàrín èdè àti ẹ̀kọ́.

## Èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè àbínibí.

Yorùbá ni èdè àbínibí àwọn ọmọ káàárọ̀-o-òjíire ní ti pé èdè yìí nì wọ́n gbọ́ jù lọ, òun nì wón fi ń ronú, òun ní wọ́n fi ń lálàá, tí wọn fi ń jẹun àti ohun gbogbo tí ó jẹ mọ́ ayé wọn; kódà, bí wọn ó bá sọ èdè mìíràn, wọn ó kọ́kọ́ rò ó lédè abínìbì yìí ná. Èdè àbínibí ni àwọn onímọ̀ èdè pè ní èdè àkọ́kọ́ (L1). Èdè tí ọ́mọ kọ́kọ́ gbọ́ tí ó sì ní ìmọ̀ rẹ̀ ju lọ ni ó jẹ́ èdè àkọ́kọ́ fún un. Èyí tí ó tún gbọ́ tẹ̀lé e ni èdè àkọ́kún-tẹni (L2).

## Èròǹgbà fún kíkọ́ èdè Yorùbá ní ilé-Ẹ̀kọ́.

Ìdí pàtàkì tí a fi ń kọ́ èdè ni ki a le lò ó láti gbé èrò àti ìfẹ́ ọkan ẹnì jáde yálà ní ọ̀rọ̀ ẹnu tàbí kíkọ sílẹ̀ lọ́nà tí yóò gbà yé ẹni tí ó gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu wa tàbí ẹni ti ó kà ohun ti a ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀. Èròǹgbà fún kíkọ èdè kò yàtọ̀ sí èròǹgbà gbog-boogbò fún ẹ̀kọ́. Ìdí ni pé ohunkohun ti ìlepa ẹ̀kọ́ bá jẹ́ lórí akẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan naa ni èròǹgbà ẹkọ́ èdè lórí akẹ́kọ̀ọ́ náà, níwọ̀n ìgbà tí ó ṣe pé èdè ni irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ yóò lò láti ṣàlàyé tàbí àgbéyọ àwọn ohun wọnnì tí ó ti kọ́.

Ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, ìwé atọ́nà fún Ètò Ẹ̀kọ́ ilẹ̀ Nàìjíríà (NPE, 2004) jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé èròǹgbà fún ẹ̀kọ́ èdè ni láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ó pegedé nínú mímọ̀ọ̀kọ àti mímọ̀ọ̀kà. Yálà ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, tàbí ti girama, ohun ti ó gbọ́dọ̀ jẹ olùkọ́ lógún ni kíkọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní èdè, pàápàá jùlọ, èdè abínibí lọ́nà tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò fi le lo èdè náà pẹ̀lú ìrọ̀rùn ní sísọ lẹ́nu àti ní kíkọ sílẹ̀.

## Àwọn ìlànà fún kíkọ́ èdè àbínibí.

Olùkọ́ ède Yorùbá gbọ́dọ̀ jẹ́ enì tí ó ní ìmọ̀ tí ó jinlẹ̀ nínú èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè àbínibí, kì ó tó ó lè tayọ gẹ́gẹ́ bí olùkọ́. Ó sì níláti fì àwọn ìlànà tó ń ṣàkóso ẹ̀kọ́ èdè gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí sọ́kàn bi yóò bá jẹ́ olúkọ tó pọ́jú owó gẹ́gẹ́ bí èrò Awoniyì (1983):

a. *Kíkọ́ ni a máa ń kọ́ èdè àbínibí, kì í ṣe àjogúnbá.*

Kíkọ ni a máaá kọ́ èdè, kì í ṣe ohun tí àjogúnbá. Gbogbo ọmọ tí ẹya ara rẹ̀ dá pé, tí a sì bí sí àyíká tàbí àwùjọ amédèlò ló ní àǹfààní látì kọ́ èdè ti a ń sọ

ní àyíka rẹ̀. Ọmọ Yorùbá tí a bí sí àwùjọ́ Yorùbá, ní àǹfààní láti kọ́ èdè náà ní àkọ́dunjú.

*b. Ẹ̀kọ́ èdè àbínibí máa gba àsìkò púpọ̀.*

O máa ń gba àsìkò púpọ̀ ki ọmọ ó tó ó dáńgáájíá nínú ìró ohùn lílò, ìhun àti ìtùmọ̀ tí ó so mọ́ ọ̀rọ̀ inú èdè àbínibí rẹ̀. Ó máa ń tó oṣù kejìlá sí ìkẹ́ẹ̀dógún ki ọmọ tó ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ sísọ. Ṣùgbọ́n ṣáájú èyí, ọmọ yóò ti máa gbìyànjú nípa àwọn ìgbésẹ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀ sísọ bí i igbe kíké àti ìsọ àìgbédè. Lẹ́yin èyí ni yóò máa sọ ọ̀rọ̀ já gaara, tí yóò máa fún wọn ní ìtumọ̀, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀, yóò máa ṣèdá gbólóhùn, yóò sì máa ṣe àtúnṣe sí bí o ti ń lo ọ̀rọ̀ àti gbólóhún bí ojọ́ ti ń gorí ọjọ́.

Gẹ́gẹ́ bí èrò Bello (2001), igbe kíké ni ìgbésẹ̀ kínní ti ọmọ máa ń gbe nínú akitiyan àti sọ̀rọ̀. Kíké ti ọmọ ń ke sì máa ń ran àwọn ẹ̀yà ara ifọ̀ lọ́wọ́ ni. Oṣù kẹta ni ọmọ yóò ti máa kùn yunmuyunmu láti gbé èrò rẹ̀ jáde.

Bello (2001) fi kún un pe láàrìn oṣù kẹrin sí ìkẹsàn-an (4-9) gbogbo ìrò tí ó wà nínú ède ni ọmọ yóò gbìyànjú láti gbé jade bí o tilẹ̀ jẹ̀ pe kò ní ìtumọ̀ sí àwọn olùgbọ́.

Ó tún fi kún un pé:

- Bi ọmọ bá pé ọdún kan, ọmọ yóò ti má a pe àwọn ọ̀rọ̀ kan ṣùgbọ́n o lè lo ọ̀rọ̀ kan láti dúró fún ohun púpọ̀. Bí àpẹẹrẹ lílo "màmá" láti dúró fún gbogbo obìnrìn tàbí lílo "mẹ́ẹ̀" láti dúró fún gbogbo ẹranko.
- Bí ọmọ bá tó ọdún kan ààbọ̀ sí ọdún méjì ($1^1/_2$–2) yóò máa lo àpólà ọlọ́rọ̀ méjì láti dúró fún odindi gbólóhùn. O lè sọ pé "mótò dádì". Bí mọ́tọ̀ baba bá tilẹ̀ tó mẹ́rin, ọmọde yìí kò lè fi atọ́ka ọ̀pọ̀ tàbí ẹyọ hàn.
- Láàrín ọdún keji àti ẹ̀kẹta (2-3) ọmọ ti le lo gbolóhun to jù ọ̀rọ̀ méjì lọ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pe gbólóhún náà kò kúkú kún tó. Bí àpẹẹrẹ, "Bọ̀dé, Fila dádì" tí o túmọ̀ sí "Bọ̀dé, fila dádì nìyẹn".
- Ìgbésè to kẹ́yìn a máa wáyé nígbà tí ọmọ bá pé ọdún kẹ́ta sí ìkẹrin. Lásìkò náà, ọmọ le sọ ọ̀rọ̀ já gaara ju ti àtẹ̀yìnwá lọ, ó le sọ gbólohùn kíkún, ó lè fi ìyàtọ̀ hàn láàrín ẹyọ àti ọ̀pọ̀; ọkùnrín àti obìnrin, ènìyàn àti ẹranko abbl. (Bello, 2001:25 &26).

*d. Kíkọ́ èdè àbìnibí jẹ́ ìmọ̀ọ̀ṣe.*

Ìmọ̀ọ̀ṣe ni èdè kíkọ. Iṣẹ́ ọpọlọ àti lílo àwọn ẹ̀yà ara ìfọ̀ ni èdè kíkọ́ jẹ́. Kíkọ́ èdè àbínibí gbà pé kí ènìyàn gbọ́n ṣáṣá, ó gba ìrònú, o sì gbà pe ki ènìyàn tètè máa ránti ohun tí ó ti kọ́ tẹ́lẹ̀. Bẹ́ẹ gẹ́gẹ́, bí ènìyàn bá ṣe ń dàgbà sí máa ń ni ipa lori ìmọ̀ọ̀ṣe nínú èdè lílò. Àwọn ẹ̀yà ara ìfọ̀ pàápàá gbọ́dọ̀ dàgbà dé àyé kan kí ọmọ tó ó lè máa sọ̀rọ̀ dáradára. Bí àpẹẹrẹ, ètè, eyín, ahọ́n, imú, àfàsé, tán-án-ná, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ti gbọ́dọ̀ gbó dé àyè kan kí ọmọ tó ó lè máa sọ̀rọ̀ já

gaara. Àwọn ọ̀rọ̀ bí i ìre, ọlọ àti àràbà a máa ṣòro ó pè bí ọmọdé ko ba tí i 'hu' eyín iwájú.

*e. Ìsínnijẹ lọmọdé fi ń kọ́ èdè àbínibí.*

Ọmọdé a máa kọ́ èdè àbínibí nípasẹ̀ ìsínijẹ. Èyí nì pé ó ń gbọ́ bí àwọn àgbà tí ó ń bá gbé ti í sọ̀rọ̀, ó sì ń gbìyànjú látì só ọ́ bí i tiwọn. Àwọn àgbà a sì máa tọ́ ọ sọ́nà bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ

*ẹ. A kì í kọ́ èdè àbínibí ẹni tán*

Kò sí bí ènìyàn ti ṣe le mọ ohun gbogbo nípa èdè abínìbí rẹ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ tuntun, ìpèdè tuntun, èrò tuntun a máa wáyé, fún kíkọ́. Olùkọ́ èdè gbọ́dọ̀ wà lójúfò láti mọ àwọn ohun titun wọnnì.

*f. Ìmọ̀ èdè àbínibí a maa ní ipa lórí kíkọ́ àwọn èdè mìíran.*

Èdè àbínibí dàbí òjìji, kò ṣe é lé sọnù. Nítorí náà, ìmọ̀ èdè àbínibí ẹnii, ìró ohùn, ìhun àti àwọn ìtúmò tó somọ́ ọ̀rọ̀ a máa ni ipa lórí bi a ti ṣe ń lo èdè mìíran. Ìkọlura a sáábà máa wáyé. Àwọn ẹ̀yà Yorùbá bí i Ọ̀yọ́ àti Ìbàràpá kì í lè pe àwọn ìró èdè Gẹ̀ẹ́sì bí i /ch/ àti /v/ wọn a si fi ìró /s/ àti /f/ ti inu èdè àbínibí wọn rọ́pò wọn. Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ tí won kì í lè pè dáradára nì" ṣọ́ọ̀ṣi" ti wọn máa n pè nì "sọ́ọ̀si" Ọ̀rọ̀ bí i "chair" (àga) nì wọn ń ṣì pè ní "síà"; bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọ̀rọ̀ Gẹ́ẹ̀sì "vice" ti wọn máa ń pè ní "fice", níbi tí wọ́n ti fi ìró /f/ dípò ìró /v/.

*g. Imọ èdè àbínìbí a máa jóbà*

Bí ènìyàn kò bá ń lo èdè àbínìbí rẹ̀ ki ó máa ṣe ìdárayá nínú rẹ̀, bó pẹ́, bó yá, èdè náà lè jóbà tàbí kí ó kú nínú rẹ̀, kì o sì di ohun ìgbàgbé. Irúfẹ́ ènìyàn bẹ́ẹ̀ a sì di àlejò gòdògbò ní agbègbè rẹ̀.

*gb. Èdè àbínibí kò dúró sójú kan*

Ìyípadà a máa dé bá gbogbo èdè láti ìgbá dé ìgbà, bí ọ̀rọ̀ titun ti ń jẹ yọ ni a o máa gbọ́ àkànlò èdè titun, ìpèdè tìtun, òwe títun àti, bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà mìíran, àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ a máa pa ìtumọ wọn dà, bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ ni àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn tí a ti ń lò tẹ́lẹ̀ a di ohun ìgbàgbé. Èrèdí ìyípada tí a tọ́ka sí kò ṣẹ̀yìn ìdàgbàsókè nínú ẹ̀ètò ẹ̀kọ́, ọrọ̀ ajé àti ètò òṣèlú. Nígbà mìíràn, àwọn ọ̀kọ́rin ni wọ́n máa ń gbé ọ̀rọ̀ titun jáde nínú orin wọn. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ yìí, "ẹ̀lẹ̀" ní àtijọ́ tọ́ka sí ojú ara obìnrin, ṣùgbọ́n àsìkò kan wà ti ó tọ́ka si obìnrin gan-an. Bí a bá ń gbọ́ "laju ẹ́" ìpèdè títun tó ń ki ní nílọ̀ láti kíyèsára ni eléyìí. Olùkọ́ èdè àbínibí gbọ́dọ̀ fi gbogbo nǹkan wọ̀nyìí sọ́kan bi yóò bá jẹ́ olùkọ́ tó pójú owó.

## Àkóónú ẹ̀kọ́ èdè àbínibí

Ìpele ẹ̀kọ́ ti akẹ́kọ̀ọ́ wà ni yóò tọ́ka sí àkóónú ohun ti olùkọ́ yóò kọ́ akẹ́kọ̀ọ́. Ìpele-ẹ̀kọ́ yòówù kí ó jẹ́, àwọn ohun tí ó ṣe kókó ní a ó tò lẹ́sẹ-lẹ́sẹ níhìn-ín:

*a. Ìpín kínní: èdè Yorùbá: O yẹ kí olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ ó ní ìmọ nípá:*

i. Ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ìdàgbàsókè ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá pàápàá jùlọ nípa bí èdè Yorùbá ṣe di kíkọ sílẹ̀, àwọn ìjọ ẹlẹ́sìn, àwọn Òyìnbó aláwò funfun àti àwọn àjọ tí wọ́n kópa nínu ìdàgbàsókè ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá, àti ipò tí èdè Yorùbá wà nínú ètò ẹ̀kọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní àsìkò yìí.
ii. Ìṣesí ohùn Yorùbá: Ṣíṣe àgbéyẹ̀wò fáwẹ́lì, kọ́ńsónáǹtì, ohùn orí-ọ̀rọ̀ ìpa-jẹ-ohùn àrànmọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
iii. Àgbéyẹ̀wò àkọtọ́ èdè Yorùbá: ti àtijọ àti ti ode òní, èdè ìperí Yorùbá.
iv. Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀: Ọ̀rọ̀-orúkọ, ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀ arọpo orukọ́, ọ̀rọ̀ ìṣe, ọ̀rọ̀ àṣàpèjúwe, ọ̀rọ̀-atọkún, ọ̀rọ̀ àpọ́nlé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
v. Àáyán ògbúfọ̀.

*b. Ìmọ̀ọ́ṣe nínú èdè: Ó yẹ ki olùkọ́ ó kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ nì ìmọ̀ọ́ṣe wọ̀nyìí:*

i. Ìmọ̀ọ́ṣé Nínú Ìfetísílẹ̀: Ìdánikẹ́kọ̀ọ́ yóò da lórí àgbọ́yé, àwọn ohun ti ó ń ṣe okùnfà àti ìdíwọ́ fún àgbọ́ye, àti ojùṣe olùkọ́ ní kíkọ ìmọ̀ọ́ṣe nínú ìfetísílẹ̀.
ii. Ìmọ̀ọ́ṣe Nínú Ọ̀rọ̀ Sísọ: Ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ yóò jẹ mọ́ pípe ìró èdè darádará, pípè àti sísọ ọ̀rọ̀ já gara, bí a ti ń sọ̀rọ̀ láwùjọ, ìtàn sísọ, ewìi kíké àti ìròyìn ṣíṣe. Ìbáṣepọ̀ wà láàrín ìfetísílẹ̀ àti ọ̀rọ̀ sísọ, nitorí pé ìmọ̀ọ́ṣe èkínní máa ń ṣe ìrànwọ́ fún ìmọ̀ọ́ṣe nínú èkejì.
iii. Ìmọ̀ọ́ṣe Nínú Ìwé Kíka: Ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ yóò dá lórí àkàyé, ìwé àkànjìnlẹ̀, àti yíyára kàwé àti onírúurú ọ̀nà ti a ń gbà kàwé.
iv. Ìmọ̀ọ́ṣe Nínú Ìwé Kíkọ: Olùkọ yóo kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní àwọn ọ̀nà ti a ń gba kọ ìwé pàápàá jùlọ, ètò ìwé kíkọ, èrò tí a gbé kalẹ̀, pàápàá júlọ nínú àròkọ kíkọ, ìlò èdè, bí a ti n jabọ̀ ìpade, lílo ìlànà kánọ̀kò làti kọ̀wé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

*d. Àṣà: Lábẹ́ ìsọ̀rí àṣà ni a ó ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwon wọ̀nyí:*

- Orírun àwọn ìran, orílẹ̀ Yorùbá
- Ètò ìjọba ìbilẹ lọ́jọ́un àti tòde òní
- Aṣa ìgbéyàwó, ìsọmọloruko, ìsìnkú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá.
- Èto Ìranra-ẹni-lọ́wọ́ bí í ọ̀wẹ̀, àáró, ẹgbẹ́ alafọwọ́-sọwọ́pọ̀.

*e. Lítíréṣọ̀ Lédè Yorùbá.*

Àgbéyẹ̀wò yóò wáyé lórí lítíréṣọ̀ alohùn àti lítíreṣọ àpìlẹkọ, yálà ìtan ọlọ́rọ wuuru, ewì tabí eré oniṣe.

## Ọgbọ́n Ìkọ́ni

Ọ̀nà méjì nì a ó pín ọ̀gbọ́n ìkọ́ni sí:

a. Ọgbọ́n ìkọni gbogboogbò
b. Ọgbọ́n Ìkọ́ni ajẹmédè.

## Ọgbọ́n Ìkọni gbogboogbo

Ọgbọ́n ìkọ́nì gbogboogbò jẹ́ èyí tí a máa ń lò láti kọ́ oníruurú iṣẹ́ yálà ó je mọ́ èdè tàbí kò jẹ mọ́ ọn. Lára ọgbọ́n ìkọ́ni bẹ́ẹ̀ nì a ti rí:

i. Ọgbọ́n ìfìdani-lẹ́kọ̀ọ́-kọnì
ii. Ọgbọ́n ìkọ́ni ẹlẹ́gbẹjẹgbẹ
iii. Ọgbọ́n ìfìbéèrè-kọ́ni
iv. Ọgbọ́n ìfijíròrò-kọ́ni
v. Ọgbọ́n ìfiṣẹ́ àkànṣe kọ́ni
vi. Ọgbọ́n ìkọ́ni ajẹmábẹ̀wò
vii. Ọgbọ́n ìfolùkọ́-púpọ̀-kọ́ni.
viii. Ọgbọ́n ìforin-kọ́ni
ix. Ọgbọ́n ìferé-oníṣe kọ́ni
x. Ọgbọ́n ìfètò-àkànṣe kọ́ni
xi. Ọgbọ́n ìfidanìlẹ́kọ̀ọ́ ọrí redio/telifiṣàn kọ́ni àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

(Olu-Aderounmu, et al 1990; Ayélàágbé, 1996; Makinde, 1997).

*i. Ọgbọ́n Ìfidanilẹ́kọ̀ọ́ Kọ́ni:* Èyí ni olùkọ́ máa ń ṣàmúlò láti fi gbogbo ìmọ̀ rẹ̀ lórí orí-ọ̀rọ̀ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ílò ọgbọ́n ìdanilẹ́kọ̀ọ́ báyìí sì wọ́pọ̀ ní àwọn ílé-ẹkọ́ gíga bí í Yunìfasìti tàbí àwọn ìlé-ẹ̀kọ́ olùkọnì onípò kínní. Olùkọ́ ni ológ-bodò ìmọ̀, ìyẹn ni pé òun nikan lo mọ̀-ọ́n tan, kì í sààba sí àyè fún akẹ́kọ̀ọ́ láti bèèrè ohun tí kò yé wọn lọ́pọ̀ ìgbà, olùkọ́ yóò kan máa kọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ ni, yálà ohun tí ó ń kọ́ wọn wúlò tàbí kò wúlò. Nígba ti idánìlẹ́kọ̀ọ́ yóò fi parí, ó ṣé e ṣe kí ó ti rẹ ọ̀pọ̀ àwọn akẹ̀kọ̀ọ́. Bí olùkó bá wa bèèrè bóyá ó yé won. tàbí kò yé wọn ogunlọ́gọ̀ wọn á sì hó gèè pé "ó ti yé wa." Bí o ti wù kì aléébù ọ̀gbọ́n ìkọ́ni yìí pọ̀ tó, o wúlò fún pípe abẹ́nà ìmọ̀ waá sí kíláàsi láti ṣe ìdánìlẹkọ̀ọ́ fún olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ lórí orí ọ̀rọ̀. O le jẹ̀ orí-ọ̀rọ̀ tó jẹ́ mọ́ àṣà, lítíreṣọ tàbí gírámà. Àfo a máa ṣí sílẹ̀ fún ìbéèrè àti ìdáhùn, èyí ti yóò jẹ́ kì àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kó ìpa nínú ìdánílẹ́kọ̀ọ́ náà.

*ii. Ọgbọ́n Ìkọ́nì Lẹ́lẹ́gbẹ́jẹgbẹ́:* Àmúlò ọgbọ́n ìdánilẹkọ̀ọ́ yìí gba ọ̀pọ̀ akitiyan láti ọ̀dọ̀ olùkọ́. Olùkọ́ yóò pín wọn lọ́wọ̀ọ̀wọ́ tàbí lẹ́lẹ́gbẹ́jẹgbẹ́, gẹ́gẹ́ bí i wọ́n ṣe já fáfá si, yóò sì rí i pé ẹ̀gbẹ́ kan kò pọ̀ jù àwọn yòókù lọ. Ọ ṣe é ṣe kí iye obìnrin tàbí ọkùnrin nínú ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan ó dọ́gba. Nígbà mìíràn, ohun ti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá kọ́ láàrín ara wọn máa ń tètè yé wọn, ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan à sì ni olórí tí ó já fáfá. Àǹfààni pàtàkì tí ó wà nínú àmúlò ọgbọ́n ikọ́nì yìí nì pé o mú kí ó ṙorùn fún olùkọ́ láti bójú tó ìwọ̀nba akẹ́kọ̀ọ́. O sì tún fi àyè gba ajọ̀ṣepọ̀ tó dán mọ́rán láàrín àwọn ọmọ ẹgbẹ́. O ń jẹ́ ki àwọn ọmọ ẹgbẹ ó kópa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti nìtorí pe ìdíje lè wáyé láàrin ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́, gbogbo ọmọ ẹgbẹ́ ni yóò fẹ́ ki ẹgbẹ́ ti wọn ó gbégbá oró-kè. Aléébù ọgbọ́n ìkọní yìí pe àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè máa jowú ara won, kí àwọn ẹgbẹ́ tó ń gbegbá orókè ó rí ara wọn bí ọlọ́gbọ́n, kí ẹ̀mì ìfa sẹ́yìn sì bà lé àwọn ti kò mókè.

*iii. Ọgbọ́n Ìfibéèrè Kọ́ni:* Ọgbọ́n ìfibéèrè kọ́nì wúlò púpọ̀ fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ajẹmédè. Ìló ìbéèrè ní ìbẹ̀rẹ̀ ìdánílẹ́kọ̀ọ́ ni olùkọ́ máa ń lò láti wádìí ohun tí akẹ́kọ̀ọ́ ti mọ̀ tàbí tí wọ́n tí kọ́ sẹ́yìn, ìbéèrè ààrín ìdánìlẹkọ̀ọ́, èyí ti olùkọ́ ń lo láti ta akẹ́kọ̀ọ́ jí láti le máa fi ọkàn bá ìdánìlékọ̀ọ́ lọ àti ìbéèrè ìparí ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ ní olùkó ń lò láti wadìí bóyá olúkọ́ kẹsẹ́ járí lórí èròǹgbà ìdánìlẹ́kọ̀ọ́. Bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ba ṣe dáhùn àwọn ìbéèrè, ni olùkọ́ yóò fi mọ̀ bóyá yóò tún kókó ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ kọ́ tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Yálà ìbẹ̀rẹ̀, ààrin tàbí òpin ìdánìlẹ́kọ̀ọ́, irúfẹ́ ìbéèrè ti olúkọ bèèrè gbọ́dọ̀ ní àwọn àmuyẹ kan:

- Ìbéèrè kò gbọ́dọ̀ ga jù ọjọ́ orí tàbí òye àwọn akẹ́kọ̀ọ́.
- Ìbéèrè kò gbọ́dọ̀ gùn lágùnjù kì ó má baà fa pọ́nna.
- Ó gbọ́dọ̀ jẹ́ kì akẹ́kọ̀ọ́ ó ro àròjìnlẹ̀ àti àrògún.
- Ìbéèrè kò gbọdọ̀ ní ìdahùn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ko yẹ kí olùkọ́ ó dárúkọ ẹni kan ní pàtó kí ó tó ó bèèrè ìbéèrè.
- Olùkọ́ kò gbodọ̀ fa ìbínú yọ sí akẹ́tọ̀ọ́ tí ó bá gbé ìbéèrè gbàgi, kàkà bẹ́ẹ̀, kì ó gbóríyìn fún akẹkọ̀ọ́ pé ó tìlẹ gbìdánwò láti dáhùn.

Bí a ba lo ìbéèrè bi ó ti yẹ, o wúlò nínu ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ nítorí o máa ń ṣe àsopọ̀ ohun ti a ti kọ́ tẹ́lẹ̀ mọ́ èyí ti a ṣẹ̀ṣẹ̀ ń kọ́, o máa n jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ó lè ṣe ìgbéléwọn ara rẹ̀. Olùkọ́ pàápàá le ṣe odíwọn bí o tí ṣe àmúlò ọgbọ́n ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ ti ó péye sí. Ibéèré a máa mu ki akẹ́kọ̀ọ́ ó ranti ẹ̀kọ́ àtẹ̀yìnwá

*iv. Ọgbọ́n ìfijírorò kọ́ni:* Kò sí orí-ọ̀rọ̀ ti a kò le fi ọgbọ́n-ìkọ́ni yìí ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Kí olùkọ́ ó kọ orí-ọ̀rọ̀ sí ara pátákó ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ ni, ki o si máa béèrè ìbéèrè atọ́nà lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ki wọ́n sì máa kópa nii. Bi àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ba ti ń jíròrò lórí orí-ọ̀rọ̀ náà, olùkọ́ yóò máa ṣe àkọsílẹ̀ àwọn kókò ọ̀rọ̀ tó bá jẹmọ́ orí-ọ̀rọ̀ ti ó sì mọ́gbọ́n-dání sorí pátákó ìkọ̀wé. Ọlúkọ́ ni yóò dúró gẹ́gẹ́ bí atukọ̀ àti olóòtú ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ń ṣàlàyé ara won tàbí ṣàtakò ara wọn lórí orí-ọ̀rọ̀ ti a gbé ka iwájú wọn. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lo ń kó ipa ti ó pojú nínú ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ nibí tí a bá ti lo ọgbọ́n ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ yìí.

*v. Ọgbọ́n ìfiṣẹ́ àkànṣe kọ́ni:* Ọgbọ́n ìkọni yìí wúlò nígbà tí olùkọ́ bá gbé iṣẹ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yálà lẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí lẹ́lẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ láti gbé ohun kan ṣẹ tàbí láti ṣe ìwádìí to la ìgbohùnsílẹ̀, àti jíjábọ̀ ìwádìí lọ. Dájúdájú akẹ́kọ̀ọ́ ló máa ń kópa jùlọ nínú ètò náà, ohun tí ó bá sì ṣe á máa yé e yéké-yéké.

*vi. Ọgbọ́n ìkọ́ni ajẹ́mabẹ̀wò:* Ọgbọ́n ìkọ́ni yìí wúlò fún kíkọ àṣà àti ìṣe Yorùbá. Bí a ba ń kọ́ iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá, a lè kó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ sí ibùdò iṣẹ́ náà. Àpẹẹrẹ ibùdó ti a perí náà ni ẹbu àdí, ẹbu ọṣe dúdú, ìdí òfi (níbi ti a tí ń hun òfí) àti bẹ́ẹ̀ lọ. A le kó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ sì àwon ibi pàtàkì-pàtàkì tí a ti bá pàdé nínú ìtàn. Àpẹẹrẹ ni Àpata Olúmọ ti ìlú Abẹ́òkúta, ojúbọ Ọṣun ní ìlú Òṣogbo, afara odò Ọya àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ́.

*viii. Ọgbọ́n ìfórin-kọ́ni:* Orin ṣe pàtàkì káríayé. Orin a máa wà ní ìrántí fún ìgbà pípẹ́, o sì wúlò púpọ̀ nínú ẹ̀kọ́ èdè. Ṣàṣà nì ìsọ̀rí ẹ̀kọ́ èdè ti a kò ti le ṣe àmúlò orin. A le fi kọ́ òǹkà. Bí àpẹẹrẹ:

Ení bí ení, lọmọdé ń kawó
Èjì bí èjì, làgbàlagbà ń tayò
Ẹ̀ta bí ẹta, ẹ jẹ ká tara wa lọ́rẹ
Ẹ̀rin bí ẹ̀rin, ẹnì bá rín nì là á rín
Àrún bí àrún, Ọba má ṣe wa larungún, abbl.

A le fi orín kọ́ ẹ̀kọ́ nípa ìlera, a lè fi kọ́ ìró ohùn, a le fi orin kọ́ ìṣírò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

*ix. Ọgbọ́n ifére oniṣe kọ́nì:* Èyí ni ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ ti a ṣe ààtò rẹ̀ sílẹ̀ yálà ní kíkọ sílẹ̀ tàbí ti a gbà sílẹ̀ lórí fọ́nrán ìgbóhùn-kọ́ tàbí fọ́nran móhùn-máwòrán. Nínú ètò rẹ̀, ọgbọ́n ìfetò-àkànṣe kọ́ni máa ń ní ìfáárà, ìdáńwo ìṣáájú, àkànṣe iṣé, ìgúnlẹ̀ àti ìdánwò ìparí ìdánìlẹkọ̀ọ́. Akẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfààní láti máa bá ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lọ bí ó bá ti fẹ́. Irúfẹ́ ọgbọ́n Ìkọ́ni yìí wúlò fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àbọ̀ṣẹ́ (Part-time Students) ati àwọn tí wọ́n n bẹ lọ́nà jínjìn (Distance learners). Ìdánwò ìbẹ̀rẹ̀ jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ó mọ ipò tí ó wà tàbí ìmọ̀ àtẹ̀yìnwá rẹ̀, nígbà tí ìdánwò ipari ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ wúlò fún un láti mọ̀ bí ẹ̀kọ́ náà yé e dáradára.

*vii. Ọgbọ́n Ìfolùkọ́-púpọ̀ kọ́ni:* Nítorí pé ọgbọ́n kò pin sí ibi kan, àwọn olùkọ́ bí i méjì tàbí mẹ́rin le pawọ́ pọ̀ láti kọ́ iṣẹ́ kan. Olúkúlùkù ni yóò ti mọ oríọ̀rọ̀ ti òun yòó kọ́. Èyí máa ń jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ó gbádùn ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ nítorí pé wọn láǹfààní láti gba ìdánìlẹkọ̀ọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn onímọ̀ púpọ̀. Nípa lílo ọ̀gbọn ìkọ́nì yìí, kò sí àyè fún olùkọ́ kan láti sọ ara rẹ di òòṣà àkúnlẹ̀bọ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pààpàá kò ní ín fẹ́ láti pa ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ jẹ́ nítorí pé olùkọ́ ni yóò ṣe ìfọwọ́sí ohun tí ó kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

*xi. Ọgbọ́n Ìfidanìlẹ́kọ̀ọ́ orí rédíò/tẹlifíṣàn kọ́ni:* Àwọn àkànṣe ètò wà lórí redio tàbí tẹlifiṣan tí olùkọ́ le wòye pé yóò ṣàǹfààní fún àwọn akẹkọ̀ọ́. Olùkọ́ yóò kan ṣètò láti mú kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ọ́ péjú si kìláàsì ní àsìko ti ètò yìí yòó gorí afẹ́fẹ́ ni kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sì gbádùn ètò náà. Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, àwọn àjọ kan wà tí wọ́n máa ń gbé ètò ìdánílẹ́kọ̀ó orí rédíò/tẹlifísàn kalẹ̀ fun àwọn akẹ́kọ̀ọ́

ilé-ẹ̀kọ́ alakọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tàbí ti ìpele ẹ̀kọ́ tó jù bẹ́ẹ̀ lọ, ó sì ní àsìkò tì ètò wọn máa ń gorí afẹ́fẹ́.

Àpẹẹrẹ ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ orí rédíò (Interactive Redio Instruction-IRI) ti àjọ USAID ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lédè Haúsá, Ìgbò àti Yorùbá ní Nàìjírìa. Nínú ètò náà, a ti fún àwọn olùkọ́ ni ìdanìlẹ́kọ̀ọ́ tiwọn láti mọ bí wọn yóò ti máa tọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti gba ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ orí redio. Àjọ yìí náà sì máa ń pín redio àti bátìrì fún àwọn ilé-ẹ̀kọ́. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti wọ́n ń gbé ọ̀nà jínjìn a máa gbọ́ ìdanìlẹ́kọ̀ọ́ àwọn olùkọ́ wọn lórí redio, tẹlifísan tàbí ẹ̀rọ ayélujára tí a mọ̀ sí Íńtánẹ̀ẹ̀tì. Bí akẹ́kọ̀ọ́ bá ni ìbéèrè, ó le lo ẹ̀rọ́ ìtẹniláago tàbí ẹ̀rọ ìntánẹ́ẹ̀tì láti bèèrè lọ́wọ́ olùkọ́.

*b. Ọgbọ́n Ìkọ́ni Ajẹmédè*

Bí a bá fẹ́ ẹ kọ́ ìwé kíkà, a lè lo nínú àwọn ọgbọ́n ìkọ́nì wọ̀nyìí:

*i. Ọgbọ́n Ìkọ́ni Amúròólò:* Nínú ọgbọ́n ìkọ́ni yìí, a máa ń ṣàmúlo ẹ̀kọ́ ìró èdè yàlá lẹ́yọ-lẹ́yọ tàbí lákànpọ̀-lákànpọ̀. Ó máa ń ran akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́, pàápàá àwọn alákọ̀ọ́-bẹ̀rẹ̀, láti kọ́ sípẹ́li ọ̀rọ̀ dáradára. A le lo ohun èlo ìkọ́ni ti ó dàbí ìró ti a fẹ́ ẹ́ kọ́.

Apẹẹrẹ ni: lílo òroǹbó látí kọ́ lẹ́ta "O"



Orísun: Makinde (2002: 118, 122).

*ii. Ọgbọ́n Ìkọ́ni amọ́rọ̀lò:* Nínú ọgbọ́n ìkọ́ni yìí, ni a tí máa ń ṣe àfihàn àwòrán pẹ̀lú orúkọ wọn ní Ìsàlẹ̀. Èyí máa ń ran akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́ láti kọ́ ọ̀rọ̀ sórí kí wọn ó tó pè é tàbí sọ́ ọ jáde.

*iii. Ọgbọ́n Ìkọ́nì amúgbólóhùn-lò:* Olùkọ́ a máa gbé gbólóhùn kalẹ̀, á si pín- ín sí àpólà-àpólà. Olúkọ́ tilẹ̀ le gé káàdì pélébé-pélébé ti a ti kọ àwọn ọ̀rọ̀ gbólóhùn sí, kí ó sì ran àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́ láti tò ó pápọ̀ kì ó sì di odidi gbólóhùn.

*iv. Ọgbọ́n Ìkọ́nì tààrà:* Èdè tí a ń kọ́ ọmọ ni á ó fi kọ́ ọmọ tààrà. Kò sí aáyan ògbúfọ̀ nínú Ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ rárá, ṣùgbọ́n olùkọ́ ni ọ̀pọ̀ iṣẹ́ láti ṣe láti mú kí ẹ̀kọ́ ó yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Olùkọ́ yóò máa ṣe àṣehanni, yóò jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe ìsọ̀rọ̀gbèsì, olùkọ́ yóò ṣe àlàyé sí ara pátákó ìkọ̀wé, yóò lo àwòrán àti pé yóò tún lo ìlànà ìsínnijẹ ìró orìṣìírísìí láti ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀kọ́.

*v. Ọgbọ́n Ìkọ́nì onítumọ̀ gírámà:* Lilo èdè àbínibí ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ́ èdè tí a ń gbé yẹ̀wò ni o jẹ ọgbọ́n ìkọ́ni yìí lógún. Ofin ajẹmédè, ìhun gbólóhùn ìnú

èdè, àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ gíríkì, ṣíṣe aáyan ògbúfọ̀ èdè tí a ń kọ́, sí èdè àbínibí tàbí láti èdè àbínibí sí èdè tí a ń kọ́ ló jẹ́ ọgbọ́n ìkọ́ni yìí lógún. Ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni a sì máa ń lò láti ṣe àtúpalẹ̀ òfin gírámà. Ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ tí a kọ́ pẹ̀lú Ìlànà ọgbọ́n ìkọ́ní yìí le kọ̀wé dáradára ṣùgbọ́n wọn kì í lè ṣe dáradára nínú sísọ èdè náà. Ó wúlò fún kílọ́ èdè àkọ́kúntẹni, ó sì wúlò fún kíkọ́ èdè àbínibi pàápàá lóde òní tó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ nì kò láǹfààní láti kọ́ èdè ìbílẹ̀ wọn ni ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀.

*vi. Ọgbọ́n Ìkọ́ni alágbọ̀ọ́wí:* Ní síṣàmúlò ọgbọ́n ìkọ́ni yìí, ìtẹnumọ́ wà fún ìdáraya ajẹmọ́ròó àti ọ̀rọ̀; ìdáraya ìhun ọ̀rọ̀ àti ìhun gbólóhùn, ṣíṣe asọtúnsọ ọ̀rọ̀ àti ní kíkọ sílẹ̀ pàápàá júlọ ṣíṣe àmúlò àwọn ohun èlò agbọ̀rọ̀sọ nínú yàrá ẹ̀kọ́-èdè (language laboratory). Ìdárayà lo jẹ olùkọ́ lógun dípò kì a máa ṣe àgbékalẹ̀ òfin èdè. Olùkọ́ a máa ṣe àmúlò àwòrán, eré oníṣe, ìsọ̀rọ̀ gbèsì, ọ̀rọ̀ akọ́nilẹ́nu àtẹ gbólóhùn láti fún akẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfààní púpọ̀ nípa bi a ti ń lo èdè. Aléebù ọgbọ́n ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ní pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ le máa sọ àwọn ọ̀rọ̀ gbólóhùn láìkọbiara sí ìtumọ̀ gbólóhùn tí wọ́n ń sọ.

*vii. Ọgbọ́n Ìkọ́ni ajẹ́mọ-Ìbánìsọ̀rọ̀:* Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti wọn tí wà ní ìpele ẹ̀kọ́ gìga ni ọgbọ́n ìkọ́ni yìí wúlo fún púpọ̀ jù, bí o tilẹ̀ jẹ́ pé a le ṣàmúlò rẹ̀ fún àwọn ọ̀jẹ̀-wẹ́wẹ́ tàbí pàgbọn-wẹ́wẹ́. Ìlò èdè pẹ̀lú ìkíyèsí bí a ti ń lò ó láwùjọ amédèlò lo jẹ wa lógun níhìn-ín. Kí í ṣe pé kí a mọ gírámà èdè nikan, ṣùgbón ìmọ̀ àṣà àwùjọ ṣe pàtàkì pẹ̀lú. Bí àpẹẹrẹ, ní àwùjọ Yorùbá, ọmọdé ti yóò ba pa òwe níwájú àgbà gbọ́dọ̀ wárí fágbà. Olùkọ́ a máa ṣe àmúlò eré oníṣe, pínpín akẹ́kọ̀ọ́ sí ẹgbẹẹgbẹ́ láti ṣe ìdáraya ajẹmédè.

*viii. Ọgbọ́n Ìkọ́nì alápapọ̀:* Gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ èdè, ó yẹ kí a mọ̀ pé kò sí ọgbọ́n ìkọ́nì tí a lè pè ní gbogbonṣe tàbí èyí tí ó dára jù. Láti yan ọgbọ́n ìkọ́nì ti a ó ṣàmúlò, orí-ọ̀rọ̀ ti a fẹ́ ẹ́ kọ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti a fẹ́ ẹ́ kọ́, àsìkò ti a ní láti kọ́ wọn, àyè ìbì ti a ó ti kọ́ wọn nì ó ṣe pàtàkì. Ó dára bí olùkọ́ bá ní ìmọ̀ nípá ọgbọ́n ìkọ́ni púpọ̀, kí ó sì lo ọgbọ́n ìkọ́ni méjì tàbí mẹ́ta ti ó mọ̀ pe yóò ran òun lọ́wọ̀ láti yege nínú ìdánìlẹ́kọ̀ọ́. Lílo ọgbọ́n ìkọ́ni ti ó ju ọ̀kan lọ bayìí ni a ń pé ni ọgbọ́n ìkọ́ni alápapọ̀.

## Ìgúnlẹ̀ àti Àbá

Bí a ti sọ tẹ́lẹ̀, 'kò sí ọgbọ́n ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ṣùgbọn àwọn ọgbọ́n Ìdánilẹkọ̀ọ́ wà' (Ọdẹrinde, 2005: 4). Níwọ̀n bí a ti mọ̀ pé ìyí padà àtìgbà-dégbà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn àbùdá èdè, ó pọn dandan kí olùkọ́ èdè Yorùbá ó máa wà lójúfò fún àwọn ìyípadà tó lè wáyé, yálà látàrí àkọtọ́, àṣà tàbí àwọn ìpèdè titun. Síwájú sí i, olùkọ́ èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ máa kópa nínú àpérò ajẹmédè lóòrèkóòrè kí o le mú ìdàgbàsóke bá ìmọ̀ rẹ̀ lórí èdè. Bí olùkọ́ bá sì ń ka àwọn ìwé tuntun àti àwọn jọ́nà àtìgbà-dégbà, dandan ni kí ìmọ̀ rẹ̀ ó gbòòrò sí i lórí èdè tí o ń kọ́. Bí Ìjọba kò bá pèsè ohun èlò akọ́nílédè, olùkọ́ gbọ́dọ̀ wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá nípà pé, 'bá ò rádàn-án, a ó fòòbẹ̀ ṣebọ'. Olùkọ́ to pojú owó ni ayọ̀ akẹ́kọ̀ọ́.

## Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí


Awoníyì, T.A. "Mother Tongue Language in practice teaching" in *Higher Education: 25 Subjects 25 Specialists* Gesinde, S.A. and Adebara D. (eds). Osogbo: Adebara Publisher Ltd, pp. 321 – 337, 1983.

Ayélàágbé, A. *Yorùbá Language and Literature Methods Ọgbọ́n-Ìkọ́nì lédè* àt*i Lítíréso Yorùbá*. Ibadan External Program Series. Ibadan: Faculty of Education, University of Ibadan, 1996.

Bello, O.R. *Second Language Teaching: Theory and Pedagogy*. Lagos: Adeola Success, 2001.

Federal Republic of Nigeria. *National Policy on Education*. Lagos: NERDC, 2004.

Kolawole, C.O.O. Language and Literature Method. University of Ibadan Distance Learning Center Series. Ibadan: DLC, 2003.

Makinde, S.O. "An Overview of Yorùbá Mother-Tongue in the Teaching and Learning in our Primary Schools" in Arohunmolase, O. (ed). *The Development of the Minority Languages in Nigeria*. Ondo: Assoc. of Nigerian Languages Teacher (ANLAT), 115 133, 2002.

Makinde, S.O. *Ọgbọ́n Ikọ́nìlédè Yorùbá: Ìwé-Iléwọ́ fún Àwọn Olùkọ́*. Lagos: Ziglag Educational Foundation, 1997.

Oderinde, B.B. Language, Communication and curriculum Issued. In Dada, A. Abimbade and Kolawole, O.O. (eds) *Issued in Language Communication and Education: A Book in Honour of Caroline A. Okedara*. Ibadan: Constellation Books, 1-14, 2005.

Olu-Aderounmu, W.O: Ogunbayo, F.O.; Adegboye, A. Ajayi, D. *Yorùbá: Nigeria Certificate in Education Series*. Ikere Ekiti: Ondo State College of Education, pp 180-214, 1990.

Yorùbá Council of Elders. Yorùbá National Day of Prayer in *Magaforce – Nigerian Tribune* 12, 823, 5, 2002.